**Appointment vacant**

1. Journey Man Printer
1. Advance Printer

Apply
Modupe Press
16 Bamgbose St
Lagos.

**IROHIN IMỌLẸ**

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

**NOTICE**

For urgent Sale!
'CROPPER' Printing Machine with Electric-Motor and Starter. 3 Rollers & 2 Chases £200, or Nearest offer, We are selling it because of space for another New Machine.
Write or Call:-
Ire-de Printing Works
9, Massey Street
LAGOS.

VOL. IIII No. 166 MONDAY JUNY 18 — JULY 24 1960 KỌBỌ KAN (1d)

# Awon egbe Alakuko ti Ariwa so fun Azikiwe pe "Gbawa lowo Ijoba yi"

**Onirohin "IROHIN IMOLE Kaduna"**

Awon egbe Obinrin ti Egbe Alakuko N. C. N. C. ni kaduna so wipe eto Ijoba Ariwa nipa pe ki won ma yo awon omo ile Naijiria ti o wa lati Gusu Naijiria ti o



DỌKITA NNAMDI AKIZIWE

SI NṢIṢẸ FUN IJỌBA ARIWA KURO NI IṢẸ, TI WỌN SI NFI AWỌN ỌMỌ ARIWA DIPO WỌN (YALA WỌN MỌ IWE ATI IṢẸ NI TABI WỌN KO MỌ) TI SỌ OPỌLỌPỌ AWỌN ỌMỌ NAIJIRIA TI GUSU DI ALARINKA, ALARINJẸ, ALAINILE, ATI ONIRANU. Ninu iwe kinikabọ kan ti awọn obinrin yi fifun Dọkita Nnamdi Azikiwe nihin, nigbati ọkọ ojurin rẹ ti o nlọ si Enugu gunlẹ sihin, awọn obinrin yi sọ wipe "Awọn ọkọ wa ti sọ iṣẹ wọn nu". Erupẹ si ti da si gari wọn. Wọn ni ojo ni awọn alaṣẹ Ijọba Ipinle Ariwa, wọn si tun jẹ ayanisọtọ. Wọn wa gba Dọkita Azikiwe ni iyanju pe ki o sa gbogbo agbara rẹ pe ki awọn ara ilẹ gusu Naijiria ti o ti fi Ariwa ṣe ile, ti wọn si ngbe Ariwa le gbadun ni ọwun, ki wọn ye dabi ẹnipe ilẹ ajoji ni wọn wa, nitori ọmọ Naijiria kanna ni gbogbo wa jẹ.

Ni idahun rẹ Dokita Azikwe sọ fun wọn pe ọrọ to di koko ni ọrọ ti wọn sọ sile yi. O ṣe ileri pe ti awọn ọmọ ẹgbẹ N.C.N.C. ba ṣe ipade ti wọn yio ṣe ni Eko ni oṣu to mbọ wọn yio gbe ọrọ na lero. Ni ibẹrẹ idahun ọrọ yi Dokita Azikiwe kọkọ ti bu ẹre lu iwe irohin Gẹẹsi kan "Economist" pe kiṣe iwe irohin atata rara atipe ikọkukọ ni wọn kọ, ninu iwe irohin na ti o jade lẹnu lọlọ yi. Iwe Irohin na kọ wipe ede aiyede yio wa larin Dokita Azikiwe ati Olotu Ijọba Apapọ Megr ma Alhaji Abubakar Tafawa Balewa, ti Dokita Azikiwe badi Gomina Agba ti Apapọ Naijiria. Dokita Azikiwe ṣe akajuwe ọrọ iwe Irohin na pe "isọkusọ" gba a ni eleyi, o wa ṣe alaye pe akọlẹ eto Ijọba Naijiria fihan gbangba iṣẹ ati aye Gomina Apapọ ilẹ Naijiria, yatọ si ti Olotu Apapọ.

## Onilu Victor Olaiya ati awon onilu N.B.C ni yio lu ilu Ominira

Ni ọjọ Ọjọ'Ru ti nṣe ọjọ kẹtala oṣu yi, ni ọsẹ tokọja ni Ijọba Apapọ fi ikede si ita pe awọn yio pe elere meji lati wa ṣe ere nibi ijo nla ti ajọyọ Ominira ni ọjọ kini oṣu Ọktoba ti ọdun ni. Awọn elere mejeji na ni awọn onilu ijo N.B.C. (N.B.C. Dance Band) ati awọn elere Victor Ọlaiya pẹlu awọn elere Irawọ rẹ (Victor Olaiya and his all Stars). Awọn Igbimọ ti o nṣe eto ajọyọ Ominira ti o ṣe imọran fun Ijọba Apapọ pe awọn elere



VICTOR ỌLAIYA

meji yi ni ki wọn pe, Ninu ikede kanna ni Ijọba Apapọ sọ wipe awọn awakọ ofurufu mẹfa lati Ilu Oyinbo wa ni ilu, lati ṣe eto bi wọn yio ti fo loju ọrun lasiko Ominira. Onirohin wa kan gbọ firinfirin wipe awọn apẹja, Obirin ọja, ojiṣẹ Ọlọrun ati awọn ọmọ ile-iwe ni Ijọba ti ṣe eto lati fi iru aiye ti Naijiria ngbe han nibi ere kan ti wọn yio ṣe ni Ọdan l'Eko lasiko Ominira. Awọn moto ti a o ṣe lọṣọ ni Onirohin wa yi gbọ wipe awọn enia yi yio wọ ti wọn yio si ṣe ifihan igbesi aiye Naijiria ni orișirișí ọna, gẹgẹbi ẹkọ wa ti lọ siwaju to,

WO OJU EWE KẸFA

# şile kan pere ra pakęti 'ASPRO' TITUN yi




Pakęti "ASPRO" titun yi wa fun tita nisisiyi mibikibi. Şile kan pere ni owo rira rę, kore ęgbogi "ASPRO" mejila ni o wa ninu rę. Nisisiyi, ęnikęni le ni "ASPRO" ni ipamo sowo lati ma a lo o ni gbara ti o ba ti ni OTUTU-IBA. O ko le mọ igbati OTUTU-IBA yio kọlu o tabi ębi rę. Mura silę.
Ra pakęti "ASPRO" titun oni şile kan loni!

**'ASPRO' nda irora**

**OTUTU-IBA DURO**


## Awon Akowe Ibode Meji Jale

Awọn akọwe kositomu meji nibi igunle ọkọ ofurufu ni Ikęja Sunday Ọmọlaja ati Macdonald Gamedede ni ile ejọ kan ni Ikęja nşe ęjọ wọn lọwọ pe wọn ji ęru awọn onişę wọn ti owo rę to igba poun, ęru na ni awọn onişę wọn tọju fun awọn onişowo kan ti orukọ wọn nję Ogunubi Trading Company. Ęleri kan nibi ęjọ yi Ọgbęni Justus Bọdunrin ti o ję akawo ni ibişę ọkọ ofurufu, sọ wipe on ko ri iwe ęri ti wọn sọ wipe awọn onisowo Ogunubi fọwọ si ko to di wipe wọn wa ko ęru wọn. Gęgębi ohun ti a nşe ęlęri yi wipe iwe ęri yi ni ohun gbọdọ ri. lati ję ki on le şe iwe gbigba fun onişowo Ogunubi, o ni nigbati Gamadede mu iwe ti aşę gbigba ęru wa fun on, on ri wipe wọn ti yi iwe na. O ni nigbati on bi ọdaran Gamdede pe kilo fa eleyi o ni nişe ni pohan ti o si purọ fun on pe wọn ti san owo. A fi ęjọ wọn si ọtunla ę o si ma gbọ bi ęjọ na ti nlọ si.

## Omoba Alexandra ti Kent



Ęniti ę nwo aworan rę yi ni Ọmọ Ọba Alexandra ti Kent, nigbati o lọ sibi ase nla kan ti awọn Ęgbę onişowo Brazil şe ni ilu Gęsi ile onję ati ti ero Savoy ni Lọndonu ni wọn ti şe ase nla yi.

Ọmọba yi pęlu iya rę Duchess ti Kent ni wọn jijọ lọ sibi ase yi. Ọmọba Alexandra yi kanna ni o mbọ wa şe aşoju iyekan rę Ọba-Birin Elizabeth keji ti Gęsi ati Naijiria ni igba ajọyọ ominira ti ilę Naijiria ni ọjọ kini oşu Ọktoba, ti o ku oşu meji abọ gedegbe.

## Awon Babala-wo yio si ile eko giga fun "Ifa" won yio si tun si ile Iwosan

DOKITA OLOYE Samuel Ontiwe Ogunloye ẹniti o kọkọ ṣe iwadi ti o jinlẹ ti o si yekoro ninu Egbogi ibilẹ ati IFA ti o si gboye wọnyi ninu rẹ P.H-D. (Canada) D.N.D.I FNFU. (Ceylon) MANI (Bombay ti o tun jẹ Ọmọ ilẹ Afrika ti o kọkọ gba oye Aiyekoro tabi Ogbokangi ti Eto Mikaila ninu Egbogi (Knight Supreme Order of St. Michael) ni ilu Mexico, ba ọkọ ofurufu pada si Eko ni Ọjọ Aje ti ọsẹ tokọja.

Dọkita Ogunloye ẹniti o kọkọ jẹ Alakoso ati Olori Ẹgbẹ awọn Babalawo Naijiria ti lọ si Canada lati oṣu Kẹfa nibiti o tun ti kọ ẹkọ ijinlẹ lori Ifa. Lẹhingbati o ti gboye orişirişi ni awọn Oye nlanla ni Londọnu, Ceylon, Scarborough, ati ọpọlọpọ awọn Ilu ti a ti nwadi ti a si ti nṣe Egbogi Ibilẹ Dokita Ogunloye tun wa gba IKO (Medal) ni Ile-Ẹkọ Giga ti Agbaiye ti Mexico (International Academic University of Mexico) Lẹhin eyi ni Dokita yi tun wa kọ bi wọn ti nṣe Koro (Pills) Egbogi ni Ile Iṣẹ ṣiṣe rẹ ni Croydon.

Pẹlu inu didun ni Dokita Ogunloye fi sọ wipe lẹhin igbati on ti sọ awọn ọrọ lori ifa ni awọn ile-ẹkọ giga ni Columbia, Scarborough ati Yorkshire, awọn akẹkọ ibẹ bẹ on pe ki on ṣe iwe lori Ifa, fun anfani gbogbo agbaiye. Fun ra ara rẹ ni Dokita Ogunloye bẹ gbogbo awọn ilu wọnyi wo, kosi si iranlọwọ kankan lati ọdọ enia kankan yala ni ti owo tabi ni ti ohun imiran mo lọ lati wadi ohun atijọ ti'ṣe ti enia dudu, mo ni ẹtọ lati kọ ile iwosan ati ile iwadi ohun ijinlẹ wa.

Ngo si kọle ẹkọ giga ti o si yekoro nipa "Ifa" kakiri Naijiria. Ẹgbẹ awọn Babalawo Naijiria faramọ Ẹgbẹ Ilera ti Gẹẹsi, ati ti awọn ẹgbẹ ọjọgbọn kakiri agbaiye. Ile Dokita Ogunloye wa ni 75, Lagos Street L'ebute-Mẹtta

Nibi ọkọ ofurufu, awọn ọmọ Ẹgbẹ Dokita Ogunloye wa pade rẹ, lehinna ni wọn wọ Mọto wa si Ile ẹsin Agọ Ijaiye Methodist, nibiti Ẹni-Ọwọ Timothy Akinkugbe ti ṣe ẹsin idupẹ fun Dokita Ogunlo e.

### O BẸRẸ LATI OJU EWE KINI

ilera wa, oja wa, ati ẹsin wa.

Awọn ẹgbẹ ati ile iṣẹ gẹgẹbi Y.W.C.A. Boys Scout ati Girls Guide E.C.N. Rebiwe ati Ports Authority ti gba lati ṣe eto ati akoso nibi ifihan yi. Ọmọba Alexandra yio wa si ibi ifihan na. Onirohin wa tun fi ye wa pe, lẹhin ẹsin ni ile Ọlọrun ti Christ Church ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ keji oṣu Ọkitoba, awọn ọlọkọ ẹyẹ yio ṣere lebute ẹhin gbẹti niwaju ile Gomina Apapọ. Awọn Saro l'Eko ti bẹbẹ lọdọ Ijọba Apapọ pe ki Ijọba jọwọ fun awọn laiye lati ṣe ẹyẹ fun Olotu Ilu awọn Sir Milton Margai ti yio wa sibi ajọyọ Ominira ni Ọkitoba.

## Okunrin Kan fi ayo pa ara re !

ABAKALIKI:- Ọdọmọkunrin arẹwa kan Uchem Akpagu ku lẹsẹkẹsẹ nihin lẹhin igbati o lu ibọn fun ara rẹ, ohun ti o fa sababi iku Ọdọ yi ni wipe o nṣe Igbeyawo rẹ, o wa mu Ibọn Sakabula lati yin fi yọ ayọ Igbeyawo yi, ki Ibọn tẹ wa yi-wọ, ti o si pa a lapa fọn. Eleyi ni o jẹ ori-keji ti ọrọ Ibọn pipania ma ṣelẹ nihin larin ọsẹ Meji. Ogunlogọ awọn ti o wa yọ ayọ Igbeyawo yi lo sokun kikoro lọ si ile wọn.

Ninu Iku ojiji Oluwa Rere gba wa nibe o!.

Ọdọ kan, John Ude tun ku bakanna nigbati o jafo ninu mọto kan ti o nlọ lati Abakaliki si Ogoja Ologbe Ude yi gẹgẹbi ọrọ ti iṣẹlẹ yi ṣẹlẹ loju rẹ wọ mọto pẹlu awọn enia mẹfa, ki jamba yi to ṣẹlẹ. Ile Iwosan Abakaliki ni o dakẹ si.

AWỌN AGỌ IPINLẸ

EYE IFIHAN NAIJIRIA

VICTORIA ISLAND
LAGOS OCTOBER 1st--22nd



Be ile eye ifihan na wo ki o si ri...

Awọn Ijọba Ipinlẹ kọọkan yio ni agọ tiwọn ninu Eye Ifihah Naijiria ti wọn yio si l'Eko ni ọjọ Idominira.

- ILA-ORUN yio fihan bi ẹkọ rere ti nṣe iranlọwọ lati gbe iṣẹ-ọwọ ati iṣẹ-agbẹ ga soke dada.
- ARIWA yio ṣe apẹrẹ bi o ti ṣe nyanju awọn iṣoro ti o wa ninu iṣẹ-agbẹ, ilera, ẹkọ ati ipese omi.
- IWỌ-ORUN ti yan ipilẹ "Ilọsiwaju" yio si ṣe alaye bi iṣẹ-owo rẹ ti ṣe ni idagbasoke titi di ọjọ oni ati bi o ti ri akoko ti o' mbọ si pẹlu itẹnumọ lori eto idagbasoke odunmarun Ipinlẹ na.

Awọn ohun-ifihan ti o fanimọra ti a o fi han ni:

- Ile akojọ-iwe ti a le si nipopada; apejuwe ago AKWETE ti Ila-Orun fun Ọlọlajulọ Alaiyeluwa Elizabeth keji Obabirin Gẹẹsi.
- Awọn Ọmọ-ogun-Ẹsọ awọn Ọba Ipinlẹ Ariwa ti o gun ẹsin. Iwe apejuwe Ile-Ariwa ti o gbooin.
- Ile-iṣẹ Ẹrọ Redio Alaworan; aworan apẹrẹ oko Co-operative lati Iwọ-Orun.

AWON IJOBA IPINLE NAIJIRIA LONI ATI TI EHIN-OLA

Printed and Published by MODUPE PRINTING PRESS 16, Bamgboṣe Street Lagos. Olotu E. A. Adeniji